OWE YORUBA

" Aṣe awọ tẹrẹ to boou ni ko jẹki a ri ikun awọn lohun, Ifẹ ti a fẹ akukọ ko denu, ibi pipaje lo mọ. Ika ko fẹ ki a ru ẹru ki a sọ, ori ẹni lo mọ ni.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

OWE YORUBA (I)

Ṣe agba, Iṣe agba, Ko ṣe agba ti Agba lo nṣe agbon. Bọko, agba lowo, iya oro. Bi a ba di agba a ye ogun nitoripe ẹrẹjẹ ni a mba agba.

VOL. XII No. 658. LAGOS, SATURDAY, JANUARY 16, JANUARY 22, 1960. KOBO MEJI (2d)

# Nigeria Yio Gba Ominira Lojo Kini Osu October 1960.

**EKO. Eyini ọrọ ti Ọlọla Alhaji Tafawa Balewa Olotu Ijọba gbogbo gbo sọ ni ipade kinîti awọn Aṣofin Ilẹ Nigeria ni ọjọ Alamisi Thursday January 14th, 1960. o wipe :-**

Awọn Igbimọ yi paṣẹ fun Ijoba gbogbo-gbo tilẹ Nigeria wipe ki o bere lọdọ Ijọba Alaiyeluwa ọba Obirin tilu eyinbo lati peṣe idasilẹ Ijoba gbogbo -gbo ninu ibẹrẹ oṣu October 1960 ki o si di ominira fun ra rẹ ninu awọn orilẹ ede, ati pe ki Ijọba Gẹsi ṣe iranlọwọ fun Ijọba ilẹ Nigeria lati di ọkan ninu awọn Ijọba Orilẹ-ede.

Awa yio gbe ẹru wiwuwo ru lati fi ye ẹgbẹgbẹrun awọn enia to ngbe ilẹ Nigeria wipe a ti to ara wa tọju ti a ko ni igbẹkẹle ẹlomiran mọ fun ilẹsiwaju, ati Idagbasokẹ lẹ wa.

Ipade ti a ṣe yi yatọ awọn ipade meji ti a ti kọ kọ ṣe, o si ṣe pataki ju lọ Awọn ipade ti a ti kọkọ ṣe, ninu ile igbimọ nla Representative jẹ eyiti a fi pe ijọba Gẹsi nija.

Mo gbe imọran dide loni mo si fẹ ki gbogbo ẹnyin igbimọ fi ẹsẹ nyin rinlẹ gbonyingbonyin loririẹ iwaju ni ao ma lọ, a ko tun ni paa ti sẹhin mọ. Mo si gbagbọ ki a ṣe akọsilẹ ọrọ yi.

Ohun ti mo fẹ so tabi ti mo fẹ ṣe ikilọ rẹ ni ọro kan ti mo fẹ so yi ou a fẹ ki nwon fi le wa lowo ni igbara ẹni silẹ ati oro ilẹ ajeji, nwonyi ṣe pataki.

# OBA ILORIN BE ILU EKO WO

Gbogbo awọn ara ati ọmọ ilu ati ilẹ Ilorin ni nwọn rọ kẹkẹ ni ọjọ Alaruba ti ṣe ọjọ kẹtala oṣu yi, lati pade Mallam Sulu Gambari ti ṣe ọba Ilọrin eyi ti oṣeṣe jẹ ni akọkọ.

Ọba Ilorin wa lati wa bẹ Igbimọ nla mejeji ti Nigeria tin mbẹ ninu Eko ti ṣe olu ilu Nigeria wo. Awọn enia jankan-janka ninu awọn Ojoye ati gbajumọ Ilọrin ba wa.

Diẹ ninu awọn Ojoye ati ijoyẹ na ni Balogun Gambari, Lemọmu Imale, Magaji Are, Magaji ngari, Malam Abdul Karimu (Alikali Agba) Alhaji Baba Oro, Ibrahima Sanda (ọwọle wode Ọba) Mallam Sanni, Okin, Alufa Momedu Ajeigbe Mallam Abodul Maliki ẹniti nṣe Akapo ijọba ibilẹ Ilọrin ati awọn ẹlomiran pelu.

Malam Sulu Gambari ti ṣe Oba Ilorin de si ọdọ Ọlọla J. M. Johnson ti ṣe Asoju Ijọba gbogbo gbo ninu eto iṣẹ ati Ilọsiwaju ilẹ Nigeria, olola Johnson si gba ni alejo.

Diẹ ninu awọn emewa ọba de si ọdọ Raphael Baba oye, awọn omiran si wọ kakiri ni arin ilu Eko.

Dajudaju ọba na yio lo ijọ meji lọ, ṣugbọn ati gbọ pe ogbadun ijọ meji na pẹlupẹlu.

Oloye Abudu Salami Agbabiaka ẹniti nṣe Ajirọba Ilorin lọ ki Ọba ni iki itẹriba.

# Enahoro Ta Ko Okotie-Eboh



Nigbati Sir Abu Bakar Tafawa Balewa ti pari ọrọ rẹ tan nipa ominira ilẹ Nigeria, o wa fi aye silẹ fun ẹniti o ba fẹ sọ.

Oloye Okotie-Eboh ti o jẹ agba fun igbimọ na dahun pe, ẹnikeni ti o ba fẹ sọ si ọrọ yen, ki nwọn jẹki o dẹgba ninu laarin oṣe.

Ibẹ ni Oloye Enahoro ti dide o si ta ko ọrọ ti o sọ wipe Haba! ko dara bẹ yẹn, ẹlowa rẹ kan nlo akoko rẹ dawe lasan ni.

Okotie-Eboh sọ wipe idi ti oṣe ṣe bẹ ni wipe, bi o ba di ẹkin ọsẹ aiye yio wa fun ẹnikeni lati sọ ti ẹnu rẹ.

Oloye Okotie-Eboh ni alabojuto inawo ilu Oloye Enahoro ni alabojuto ilu okere.

## Paga, Olopa Mu Woli Serafu Meji Ni Ilorin !

ILORIN. Li ojo ose kan ninu osu Jan. 1960, ti awa yi, nigbati awon Serafu nse isin lowo, ti awon nkorin, ti gbogbo re ndun yungba, lojiji ni a w o n olopa oba Ilorin yo si won, o si mu awon Woli ijo na meji ati die ninu awon Asiwaju won. Enia mejo ati Sekiteri won ni owo ba. Awon olopa ke si tete gba iduro fun awon enia na.

Esun ti awon olopa fi sun awon egbe Serafu na ni wipe, awon ko eti didi si ase ti oba I l o r i n pa wipe on ko fe ajeji esin kan nilu on mo.

A si gbo wipe awon ala dugbo ti o ngbe Opo Mal Street lo lo fi ejo sun wipe ariwo awon egbe Serafu losan ati loru ko jeki awon ri orun sun

### IYAWO DUN LOSINGIN, OKO TUN MI GBE

ABEOKUTA. Irohin ko to afojuba ni ti iyawo Abudu Yekini Sowunmi ati Oluranti Apinke ti o sele ni oke Jebun ni ojo 3rd osu Jan 1960 ni agbole Shose.

Awon serekode ati gbajumo ilu fi owo ati aso dabira sibe.

Agbo wipe nibi ise oko oje omi Palm Line ni Apapa n i oko iyawo yi gbe nise, ogun lo ge ninu awon ore re lo ba lo obe iyawo na ni Abeokuta.

Die ninu awon gbajumo t i o wa sibe na ni, ogbeni R.A. Akini pelu, T. Arigo, S.A. Adeogun, I.O. Ogunremi Iyafin Ogunremi omidan O. Tiamiyu, O, Ojuu-jeyi.

### OWE

Asa mba eiyele sere eiyele nyo eiye nfi iku sere. Bi omode ba nleri wipe, agba ko n i ase bi oo, o dajn pe, omode na ko le ni akisa gegebi agba.

Bi o ko sowo, joko. Bi o ko sowo joko Akisa aso g e n t e gente, akisa aso gente gente.

## S. L. Akintola Fi Okan Re Si Ilosiwaju Eko

Oloye S.L. Akintola ni o je Olotu I w o - Orun Najiria so fun apejo awon oluko ni Ibadan wipe ninu ijoba ti on ti o bereyi, on yio sa gbogbo agbara lati wa ilosiwaju eko ni l e Yoruba

Nitorina ijoba Iwo orun nfe awonoluko papa awon ti a ti ko ni ise oluko, ti ko ni ise meji tayo ise oluko, yio, si ma wa idagbasoke ile Yoruba



Ise pataki ni ise na je, nitori o n n a t i se ise oluko ri.



# O npese Agbara Ola Sile





Orun asunwọra ti ko ba mu iyọnu dani nsọ gbogbo agbara ati okun-inu di ọtun. Agbara titun ati okun-inu a si wa fun ọjọ keji. Eyi ni o mu ki ogunlọgọ awọn ọlọmọ-lẹbi fi ma a mu Ovaltine ki nwọn to sun lalẹ. agbara titun-ẹyẹ-se rẹ a ma a mu ara sile a si jẹki enia le sun asun-wọra gẹgẹbi o ti yẹ, wa a ji pẹlu ara-yiya ati pẹlu emi akọtun ati ara lile Ovaltine olokiki ti gbogbo aiye ti mọ ni onjẹ mimu aladun ti on tun ẹyẹ se





## ABAMI ERAKO BURU KU KAN WỌ ILU LỌJỌ ỌDUN TITUN

Fẹmọ ola, ira kia ni ni awọn ara ọja ni i ti onyan yan ti ko si daro gbe ohe ti ẹkukuluku enia fi ọwọ yo. Iyan n di pee-nluke ni oja kan ni Ijẹbu-Ode nigbati ẹranko buruku ya wọ ilu na, ti oja si fi bẹ tuka.

Awọn ero inu ile ilu ti o gbo irohin yi bere si gba oja ferese fo jade, popo enia so wipe nwọn ko ri iru ẹranko bẹ ri, ese lo nobi gidigba gidigba, laipe lojo irohin na gbogi kao kakiri ilu

Nigbati irohin na de etiẹbọ awọn ọdẹ ilu Ijẹbu-ode, olukuluku wọn gbe ibọn sakahuta won nwọn gaa lati yi-'i fun ẹranko elesemefa na. Awọn agbagba ilu so wipe ko sie oni tabi ana ni ẹranko na ti nwa gbe enia lo.

Lọdun ti o koja lo yi, awọn agbagba sọ pe awọn de okun fun ẹranko na lati bu inu. sugbọn si iyalenu wọn, ẹwọn kan ni okun na mu, eyi je ghogbo enia lojanu, ki awọn ọdẹ topari awari wọn lati ẹranko na, ẹran na ti torilọ igbe, o si ti lọ.

## SIKIRU ADETONA JẸ ỌBA IJẸBU-ODE

Ni ọkọ̀kerin ọsẹ ọdun titun yi ni Ijọba Iwo-Orun se ikede pe a mu omoba Sikiru Kayode Adetona fun Ọba Ijẹbu-Ode.

Omoba Adetona je omo ọdun merindilogbon, o dari wa si ile lati ilu Oyinbo nibiti o ti kọ eko iloniwọye nigbati awọn ansi ẹ yan fun ipo na.

Oba wa titun yi ni o kere jalo ninu awọn mefa enia ti won mu jade fun oye oba na nitori eka idile Anikilaiya, to je wipe iran won lokan lati je oba na.

Awọn kan ninu ebi Anikilaiya ti pe ẹjọ si ile ẹjọ nla ni Abeokuta wipe awọn kọje ẹtọrina ki ile ẹjọ fi aṣẹ si wipe ki nwọn ma mu lati je ọba. Sugbọn wọn ko ti ke je ẹjọ na.

Awọn Afọbaje yio jade lati so ọjọ wo ni oye ti o si to lati gbe Ade oba ka ni ori.

---


E MA KA IWE
IROHIN
ELETI-OFE
LỌSỌSẸ
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

# ELETI - OFE

A-NIU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
24, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFE LAGOS"
P. O Box 467 Phone 23370

VOL. XI. NO. 658. SATURDAY JAN. 16- JAN. 22, 1960


## KABO O !

Nilẹ yoruba, ni asiko atijọ bi alejo nla kan ba wọ ilu tabi enia pataki ba re idalẹ, bi o ba wa sile, awọn enia rẹ yio ma kii bayi pẹlu orin wipe:-

Ka-bọ o
Ka-bọ o
Ọmọ abilẹ sọrọ
Kilẹ lanu, Kabọ o.

Gbolohun yi ni awa Oniwe 'rohin Eleti-Ọfẹ fi ki Ọlọla Sir Harold Macmillan ẹniti iṣe olotu ijọba Gẹsi, wipe KABỌ si ilẹ Nigeria.

Gbogbo ẹnyin ọkawe wa ni yio ti gbọ nip ti abẹwo ti ọlọla yi ati iy'afin rẹ wa bẹ wa wo, fun ti ipalẹmọ ominira ilẹ wa eyiti ọjọ rẹ ku fẹrẹfẹ.

A fi ayọ ati ọpẹ fun Oluwa, a si fi idunno ki awọn alejo wa awọnyi ku ifẹ, awọn si ku ifẹ ara wọn paapa pẹlu. Ki ajọṣe wa maṣe bajẹ. kabọ o, ẹnyin ọmọ abilẹ sọrọ, kilẹ lanu kabọ.






## Obinrin Yi Ri Iwosan Lona Iyanu



Obinrin 'ti a nwo yi ilo ri iwosan gba lọna iyanu, ni igbati o saisan fun ọjọ pipẹ ti irora ko jẹki o gbadun, nigbana Dr. Geoffrey Bateman ba tẹ rọba ero Radio bọ ni imu re nipa bẹ, irora rẹ dinku o si bẹrẹ si ri alafia.

## Itan Anobi Liaṣu

### Apa 3

Lati owọ Lemọmu Ajakuta

Nigbati awọn ọmọ Israeli (yawudi) ko ri oju rere oriṣa wọn yi lati owurọ wa, awọn ṣe aṣaro larin ara won wipe awọn Babaloriṣa wọnyen ti ṣe ohun aimọ ti oriṣa na ko fẹ.
Nitorina ohun ti o yẹ ki awọn ṣe, ki oriṣa yi ma ba doju ti wọn ni wipe, ki awọn fi ida pa gbogbo awọn Babaloriṣa na Ọba paṣẹ, awọn si pa awọn Abọrẹ oriṣa Bali na.

Nigbayi ni iṣẹ na yi kan awọn awo ti awọn ro wipe, awọn ni omo-awo ti ara wọn mọ julọ, awọn bo si di oriṣa yi, awọn pe to bẹ ti ilẹ fi mi titi sugbọn oriṣa na ko mira, ko si yọ ina jade lenu gẹgẹbi o ti ma nṣe.

Bi o ti di wakati kẹrindilogun ọjọ ni Anabi Liaṣu tun wa fi wọn ṣe ẹfẹ, nigbayi inu bi Ọba o ni ki a pa wọn pẹlu.

Bi o ti di ọjọ alẹ ti ilẹ nṣu lọ, ti oriṣa Bali ko le yọ ina lenu rẹ mọ, ni Anabi Liaṣu de pelu iṣu, Koko, Esuru ati idunkun lati fi rubọ tirẹ. Ọba fun ni odindi malu kan lati fi ṣe ẹbọ tirẹ, sugbon Liaṣu kọ ko gba.

Ẹ ma ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ o kun fun irohin aladun, iyoku di ni ọsẹ ti o mbo.





## OMUTI GBACBE ISẸ I...

**KALABA.** Okunrin omuti kan ti awọn npe ni Etim Bassey, ni agbọ wipe o lu obinrin abileko kan ni ilakilu tobẹ ti obinrin na ko file dide mọ.

Awọn ọlọpa mu ọkunrin na dewaju adajọ ti oti enia gbai lori rẹ. Adajọ bere wipe, Etim, kini obinrin na se fun ọ? O dahun pe, ki adajọ fi ori ji on, nitoripe nisisiyi ti oju oti wale yi ni on to mọ pe, on lu enia, nitori on mu ọti ju.

Adajọ so wipe nje o gbagbọ wipe, bi enia ba mu ọti papọ, oti na a mu ko ni, lati sisaba je enia ba mu ọti yo, oti na ka ton le pa lakaye enia kẹta bi?

Nitorina ki o lọ gbẹwa osu mẹrin pelu isẹ wọgan.


Kere o !

A ti ni ... fun ... Jẹdi jẹdi, (Bitter Tonic Liquid of Life) Tele ... ra tire, ... obinrin, ki o to tan.

J. A. AJAO
BROTHERS
MEDICINE STORES
17, Egerton Road Lagos


## Ikomo Adeogun Mirigidin

**Apapa.** Ọgbeni S. Adeogun se ikomọ rẹ jade ni 23, Bale Street ni oke Apapa.

Lọjọ 9th osu January 1960, awọn si fun ọmọ na ni orukọ yi, SAMUSU-DIN.

Nibi ikomọ yi, awọn alase nse, onijo nje ese awọn gbajumo peju sibẹ lati Eko, Ijọra Ebutemeta, Otọ ati lati Iganmu eniti awọn fi je oye Alaga ere na ni Rasidi Arogundade Ibgakeji alaga ni J. Idahosa.

Die ninu awọn gbajumọ ti o wa sibe ni ọgbeni R.T. Ariyo, Y.A. Showunmi, B. S h i t t u egbe Mornig Stars ati gbajumọ enia lati Agege ati Abeokuto.

## Olorun Majeki Eleru Kuro Nidi Eru Re

Lẹhin igba ti baba ọmọ yi ti fi itọju ọmọ rẹ le iyale rẹ li ọwọ, omu oju kuro ninu alamọri rẹ, osi koju si iṣẹoko rẹ.

Orogun Buruku yi bẹrẹ iwa ibi pelu ọmọ iyawo rẹ to bẹ gẹ ti ọmọ na fẹrẹ sa kuro ni ile baba rẹ. Ni kutu kutu ọmọ yi yio lọ si odo lati re fa omi sile yio lọ ke ise ti ao fi dana, kio to wa bẹrẹ si se epo onjẹ ti nwon maje, on na ni y i o se awọn ise ile yoku bi ilẹ gbigba, awo fifọ, omi iwẹ fun Iyale iya rẹ ati Ọbakan rẹ.

Ninu gbogbo wahala ti omode binrin yi doju kọ onilati ya gbogbo eyin ti nka itan yi lẹnu wipe, Epo iju ati eri ti a yọ kuro ninu agbado ni onjẹ rẹ. Nigbati ebi pa fun ojo meji, oma irihin buruku yi lọ ba ẹgbọn rẹ okunrin ti iya rẹ bi fun baba omiran. Nitoripe on beru ati fi han baba rẹ.

Koni on ti ale fi ọmọ iya we, ẹgbọn re da lẹkun osi fun ni imoran ifi ori ti isoro tori wipe ore ifarati rẹ nbọ lola. Sugbon O jo fun pe ki o ma wa je onjẹ ni ọdọ on. Ọmode binrin na jẹun lodọ ẹgbọn rẹ bosi dari wa si ile, lati gbana ibẹ ni oniẹ on'ẹrẹ. Iyale iya omo yi ko din owo ibaje rẹ kuro lara omo yi, sibẹ sibẹ nise n i se ni on tunbọ ndada si lojojumo. Ebu oripirigi ni on da laso fun omo na laro losan ati ni ale sugbọn omo na ko fi eti si.

Epa nps ra rẹ o ni on pa a'a, se omo tirẹ wa nibẹ ti o joko si ori aga ibaje ati aimokan, Iya rẹ ko ko bi a ti nse ise ile ko 'sa tiji ki o je on'e ofe, ki obu omi sara ki o ti ka owo botan. Iwo iya ti o nfi omo olomo ke omo re o ha ni ranti ojo ola bi

(Wo iyoku loju ewe keje)


E MA KA IWE
IROHIN
ELETI-OFE
LOSOSE
O KUN FUN
IROHIN ALADUN


## OWE

Gidigidi kọ mọlẹ, ko ... bi ẹru ko da ... Opa agbele ko, ti ... otito ... pe ... lo mọ ẹniti ... on ... pe.


HINDU ...
Religious Art Jewelleries

Remit ... Post ... for Catalogues and ...
HINDU ... Road,
London, S.E. England

## Ape Ejo Nipa Ibo Ołola Balewa

(O bere Ninu iwe Ọjọ to koja)

Ninu ipejọ rẹ, o fi han Onidajọ wipe, ninu Ileto kan ti a npe ni Doss Baie ileto na jade esi joko ni ibiti agbe ile ibo si kodede joko nibẹ bi kose wipe o bere si şan mọ awon enia bayi wipe Eni ti ko ba ja iwe ibo rẹ sinu apoti Ọlọla Abubakare, yio lọ si ẹwọn.

O tun fi han ninu iwe ipejọ rẹ wipe ninu awọn ilu awọnyi Jarawa, Laudi, Zangam Maijuju, Gora, Barikin Tusa Fusoa Gandoma Fobor Zaboa Gari Fobor ati Federe gbogbo awon Akọwe ti on yan lati mojuto ibo fun on ni ako jẹ ki won gbadun ati şe işe wọn dede. Ju gbogbo rẹ lọ wọn fi agbara le wọn jade kuro ninu ile ibo



Ni ida keji ẹwẹ, O ni wọn kọjẹ ki awọn akọwe kankan tọle apoti ibo on lori ibiti ati ma ka ibo awọn Olomi tan ki awọn akọwe p mọlẹ lati jẹ ni iya won ti gbogbo wọn mọ ile ọlọpa.

Oti na na sun ni ikan kansi ju onidajọ asi gba pe ki gbọ ti otun a titon nipa ọrọ na.

Bakanna ni mallam Musa Shariff ẹniti ẹgbẹ Afenifẹre yan ni Arewa Muri ati mallam Aliya Dan Rini ẹniti ẹgbẹ Afẹnifẹre yan fun ilẹ Arewanga nu ẹsun wa si iwaju Onidajọ kanna, nipa iwe eru ti o nşẹlẹ ninu ti wọn pelu ti ẹgbẹ Olomi ti Olori wọn.

**Orisirisi** ẹsun ni wọn nu wa ninu ẹsun Mallam Shariff ni wipe, mọlẹru po ninu ibo ti won di. Ninu ẹsun Mallam Rini, ani wipe ati iwe ti a fi ndibo ni akowe ijoba ti o wa ni ilu Waram, Gbogbo iwe wọn je igba ati meje.

tube ge ti wọn fi da awọn ọlọpa si ọjà altori ki wọn le ma wa pale.

Iwon iba ọjọ ti awọn ọlọja na ko fi si aye pale ni ibẹ lẹ ipadanu nlanla fun wọn.

### AWỌN IGBIMỌ L.T.C. DA AWỌN ỌLỌJA PADA SI AYE WỌN

Agbọ wipe awọn Igbimọ Lagos Town Council ti gba ni imọran, wọn si ti fi aşẹ si wipe ki a yi ọja Ereko fun awọn ti wọn ta ọja ni ibẹ. Eyi jẹ ayi pada rere fun ẹgbẹ Alakuko ti ikapa Igbimọ Lagos Town Council wa ni owọ wọn.

**Nigbati** odun Keresimesi ku si dede, ti awọn ọlọja wọnyi nta ọja ọdun ni iwe ki wọn palẹmọ kuro l'ọja

### Ipade Akoko Se Awon Igbimo Ile Nigeria

Ipade awọn igbimọ aşofin meji lo şẹlẹ ni ọjọ kanna papọ ni ilu Eko, eyi ni igbimọ nla (House of Representative) ati Igbimọ Senate. (House of Senate.)

Ninu igbimọ (House of Representatives) awọn enia mejilalẹ ni ọdunrun ni o joko se igbimọ ninu ile igbimọ titun National Hall ti awọn koiti ko pari tan awon igbimo Senate si se igbimo tiwon ninu ile ti a ti nşe igbimo nla latijo ni odun.

Işẹ meji pataki ni awon Igbimo wonyi muse ninu ipade won (1) Awọn enia merinlelogoji ti nwon yan sinu igbimọ na, olukuluku won lo bura lati se işẹ won ni otitọ ati ni ododo. (2) Nwon yan Baba-ẹgbẹ fun igbimọ na.

Enia mẹrin ti nwon yan sinu igbimọ Sanate nilu Eko je eniti inu Gomina agba dun si lati yan si ipo na enia mẹrin ni Gomina yan funra rẹ sinu igbimo Senate.

Işẹ pataki ti nwon şe ninu ile Igbimo nla ni wipe ki gbogbo awon ti a yan si igbimo wa bura lati şe işẹ won lotito ati lododo. Lojo Alaruba ni Gomina agba Sir James Robertson wa si ipade igbimo na o si ba igbimọ na so akọ oro ti o je mo işẹ won. Awon igbimo mejeji lo si jijọ joko papo ninu ile igbimo National Hall, awon igbimo Senate joko lẹhin awon igbimo nla Representative.

# Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki Olotu Ijoba Ilu Oyinbo Ku Abo



Ọlọla Macmillan ti se Olotu Ijoba ilu Oyinbo ba oko ofurufu de si ilu Eko ni ọjọ kokanla osu yi, o si sọkalẹ ni Ikeja ti se ebute oko Ofurufu. Ọlọla Gomina Agba ti ilẹ Nigeria Sir James ni, pẹlu Olotu Ijoba ilu Nigeria Ọlọla Abu Bakar ati awon igbimo rẹ pe awon enia lọ lati pade rẹ. Olotu Iwe Irohin Eleti Ọfẹ ati awon Ọpọ rẹ ati awon Ọka-we yi ki Ọlọla na ati Iyawo rẹ ku Abọ, awon si tun ki gbogbo Ilẹ Nigeria ku Afojuba.

# IKEJA TOWN PLANNING AUTHORITY

## VACANCIES FOR TOWN PLANNING OFFICER AND CIVIL ENGINEER

Applications are invited from suitably Qualified persons to fill the vacant posts of a Town Planning Officer, and a Civil Engineer in the employment of the Ikeja Town Planning Authority, Ikeja.

2. SCALE OF SALARY

Town Planning Officer £1,800 x 60 - £2,040
Civil Engineer £1,500 x 50 - £1,800.

3. QUALIFICATIONS :

Town Planning Officer: Candidates must possess a professional qualification and membership in T.P.I. or R. I. B. A. with wide experience in the preparation and administration of Town Planning matters.

Civil Engineer : Candidates must possess one of the following.

(I) Recognised degree in Civil Engineering with at least 5 years post graduate experience.
(II) Associate membership of the Institution of Civil Engineers.
(III) Associate membership of recognised institution of Civil Engineering in Commonwealth Countries.
(IV) Associate membership of Institute of Municipal Engineers.

4. DUTIES :

Town Planning Officer : Successful candidates will be responsible for the town planning duties of the Authority covering Town Planning control, Design, the preparation of Schemes for Control Re-development, Industrial Estate Development, Housing, Estate Development and Neighbourhood Development.

Civil Engineer: Successful candidate will be responsible for preliminary work and supervision of all types of Engineering and construction works, including preparation of estimates.

Experience in House construction will be considered an advantage.

5. Other condition of service:

(i) In case of Expatriates appointment will be on contract only.
(ii) An outfit allowance of £60 is payable on first appointment.
(iii) Rent is payable at the rate of 10 per cent of salary when an officer is occupying Authority quarters.
(iv) Contributory provident fund at 10 per cent of salary to which the Authority will add 15 per cent.

6. Application stating age, professional qualifications, experience, previous employment and names of two referees should be sent to reach the Chief Executive Officer, Ikeja Town Planning Authority, Ikeja, not later than February, 19, 1960.

**CHIEF EXECUTIVE OFFICER**
Ikeja Town Planning Authority.


# Olorun Majeki Eleru Kuro Nidi Eru Re

(O bere loju ewe karun)

Lati igbati egbon omo ... kan yi ti fun aburo re ni ase lati wa ma jeun lodo re ni alafia ti bere si wole to ase otito ni owe ti nwon pa wipe,(Ti ebi bati kuro ninu ise obuse.)

Layi ko fa oro lo g u n g u n titi lo, gbogbo epo nu asi eri ogi ti afise onje re ni omo ... si fun ke awon opolo ti won wa ninu omi adagun ni ekun le awon.

Iwo olu ka iwe yi mura ... iwa re sugbon kio mo daju wipe ore kin gbe bere ni ... kini gbe, mase so wipe eda kan je enia omiran si je eranko, eyi

ti oba bo si ode re lati ... ore fun gbiyanju lati se ... gege bi agbara re.

Ni gbogbo igba ti omode binrin yi nse italore onjere fun awon opolo, ko mo wipe ... ni odun ni inu won, awon na si ti mura lati ran omo yi lowo ni gbogbo igba ti awon bati wipe ofe anfani awon, beni omo yi ko mo ko si ... okan re si iranlowo awon eda ... adagun omo yi.

Mase niso esan nbo wa iyoku di ose miran.

# Dr. Azikiwe Je Baba Egbe Senate.



Agbo wipe ... Baba egbe ... ni oye Baba egbe Ile igbimo Gomba gasi tin yapa ni (Senate)

Ki egbon wa Dokita Azikiwe ... tojo aye ma duradura, ... gbo ... awon ... aiye mbe ni ara wa.

A si ... fun Oba Eko Adeniji Ade II ... fi se igbakeji re na. ... aiye yi fun wa ...




AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O.BOX 599. LAGOS.

*Always ask for*
**'DE FACTO'**
*the bread with the appetising flavour*


E MA KA IWE
IROHIN
ELETI-OFE
LOSOSE
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

## ỌKUNRIN TI OJI ERE ILẸ NIGERIA TI GBA ẸWA

Nigbati iku npa ni ki li Orisa nwo. A gbọ irohin wipe Ọkunrin kan ti o njẹ Fraore ra ilẹ Gambe lọ si arin awọn Ọrẹ ti Ijẹbu ko jọ nilu Ọrọn, o ji diẹ ko ninu awọn Ere na, o ta diẹ silẹ Amẹrika, o si ta yoku sile Europe. Gbogbo eru ti Traore jiko ti lọdọ ijọba ti adọtale lẹdẹgbẹrin Pọuun.

Adajọ sọ wipe, b'enia ko ba fi oye gbe ọrọ adaran yi, ko ni tete gbagbọ wipe ejẹbi ọrọ na, Bi a ba fi oju inu wo o, enia ko ẹru jade kuro nile Nigeria o ko lọ si Ghana, si Sierra-Leon, si Las Palmss ati bẹbẹ titi o fi de Europe ati Amẹrika ati ilu miran ti awọn oni bode kan ko fi ri.

Mo gba pẹlu itẹlọrun wipe nigbati ọdaran yi de ilu Paris, ibẹ ni o gbe ta diẹ ninu awọn Ere na ti a si ri awọn ẹlẹri ijọba ti o ṣoju rẹ, nigbana bi ara Surich, New Zealand, Emil Storrer ti o ra ọkan ninu awọn ere na sọ pe ere na jọ ara eyiti on ra ọkan ninu re Adajọ ni ki o lọ si ẹwon odun meji abọ.

---

## UAC DIRECTOR RESIGNS

Mr. G. E. Graham resigned from the Board of the United Africa Company Limited on the 31st December, 1959 in order to take up special duties with the parent company Unilever Limited.

Mr. Graham was appointed to the Board on the 14th April, 1958. Previous to that he was a director of SEDEC S.A., a subsidiary company in Brussels.

# Igi Ọpẹ. Igi Owo Kọse Yo







Akọwe gbogbo gbo ti awọn ẹgbẹ olomi ni ilu Kaduna pelu olori ẹjo alatako ti Ibadan ti gba esi iwe wọn lati odo oyinbo agba ti se alabojuto idibo ti ilu Nigiria.

Akọwe olomi ni Kaduna kowe wipe ami Igi Ọpẹ ti ẹgbẹ Afẹnifẹre nlo ko basi nitoripe ojẹ ami ti a fi si ara owo sile ati owo takarda ti anna ni ilu yi, osi ni Igi Ọpẹ na ni ami ti awọn jagun jagun ati awọn olopa ti Ijọba gbogbo gbo nlo.

Esi Iwe na ti awọn ri gba ko ba ikun mu, nitori oyinbo agba ti nwọn kọ iwe si na fi ye wọn wipe (Gege bi eto ofin idibo ti ase sile ti owa ni oju ewe ori konkonle logoje (141) ese kerin ti akọsile ni ọdun ẹgba din ni mejile logoji (1958.) Ko si agbara lati yo ami tabi apere oselu kan ti ati gba ti asiti fi onte ijọba tẹ kuro, ayafi ti egbe kan baso wipe, on kọfẹ ami tabi apere na mọ.

Ni ida keji oyinbo agba alasẹ idibo tun ni agbara lati yo koro iru ami aselu ti ẹgbẹ ti ko ba yese mọ. Nitorina oyinbo agbayi gba wipe Igi Ọpẹ ti ẹgbẹ afenifere kose yo kuro ninu ami oselu nitori pe awọn ẹgbẹ yi ko so wipe awọn ko fe ami yi mo, beni awọn ẹgbẹ na si wa digbi

---

## More Oil Exploration In The West

Shell-BP has commissioned another seismic exploration party the oil search in the Western Region, where it is at work near the Ramos River, some 30 miles south-west of Warri. This brings the number of seismic parties working for Shell-BP from seven to eight—a total of over 2,000 men on exploration work alone. This is quite apart from the drilling effort and its engineering and other Services which together employ about another 3000.

The number of seismic parties working for the Company has double since oil was found at Oloibiri in 1956.

Six of the eight parties, including the new one, are operated for Shell-BP under contract by an independent firm, Seismograph Service Limited.

---

ELETI OFE D'ARABA

E MA KA IWE

IROHIN

ELETI-OFE

LOSOSE

O KUN FUN

IROHIN ALADUN




Ogun Aran ejo Inu

Aradan Worm Expeller jẹ ogun aran pataki fun ọmọde ati agba ọkunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awọn aran buruku ti o nba ọ jẹ ninu danu. Bi o ti npa aran beni o npa ẹyin wọn. Wa ra tire ki o to tan. Igo kan jẹ 2/6 Owo ọkọ si jẹ 1/.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES
18, Denton Bridge Street.
P. O. Box 2 Ebute-Metta

Printing & Published by The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street, P.O. Box 467 Lagos Phone 2937